# IPÁ TI AWỌN OBI ẸNI IWA-BI-ỌLỌRUN NÍ

**Owe 22:6; 29:15; 2 Timoteu 1:1-5; Gẹnẹsisi 18:16-19; Joṣua 24:15**

**ẸKỌ 385 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Tọ́ ọmọde li ọ̀na ti yio tọ̀: nigbati o si dàgba tan, ki yio kuro ninu rẹ̀" (Owe 22:6).**

**I Ipá ti Awọn obi Ni**

1 Awọn obi ni ipá lori ọmọ, Owe 22:6; Efesu 6:4; 2 Timoteu 3:15.

2 Ibawi n fun ọmọde ni ọgbọ́n, Owe 29:15; 10:1; 17:25.

3 Paulu sọ ifẹ rẹ̀ si Timoteu, ọmọ rẹ̀ ninu Ihinrere, 2 Timoteu 1:1-3.

4 Awọn obi Timoteu ni igbagbọ 2 Timoteu 1:4, 5

5 Oluwa fi iparun Sodomu hàn fun Abrahamu nitori ijolootọ rẹ̀ gẹgẹ bi obi, Gẹnẹsisi 18:16-19; Johannu 15:15

6 Joṣua gba awọn Ọmọ Israẹli ni imọran lati sin Oluwa, oun paapaa si pinnu lati ṣe bẹẹ, Joshua 24:14, 15; Rutu 1:16

## ALAYE

Owe igba lailai kan ti o sọ bayii pe, "Ibi ti ẹ̀ka igi ba tẹ̀ si ibẹ ni igi n tẹ̀ si", jẹ́ otitọ. Bibeli wi pe: "Tọ́ ọmọde li ọna ti yio tọ̀: nigbati o si dàgba tan, ki yio kuro ninu rẹ̀." Ipá ti awọn obi ní lori ọmọ wọn n bẹrẹ ni gẹrẹ ti wọn ba ti bi wọn. Bi obi kan ba jẹ oloootọ ti kò si tan ọmọ rẹ̀ jẹ lọnakọna, ọmọ naa yoo dagba pẹlu igbẹkẹle ti o duro ṣinṣin ninu awọn obi rẹ̀.

Ọkan ọmọde rọ̀ pupọ o si le tete tẹ̀ si ti Ọlọrun ati si ododo nigba ti obi ba bẹrẹ si i fi otitọ wọnni kọ ọ lati igba èwe. Ko si ogún kan ti o niyelori fun ọmọde ju ile ẹni iwa-bi-Ọlọrun, ani ile Onigbagbọ́. A maa gbin ifẹ ati ọ̀wọ fun Ọ̀rọ Ọlọrun sinu ọmọde.

### Ipá ti Awọn Obi Ni

A ni apẹẹrẹ ipá ti awọn obi n sà lori awọn ọmọ wọn ninu igbesi-aye Timoteu. Paulu sọ nipa ti igbagbọ ailẹtan ti o wà ninu Timoteu, eyi ti o kọ́ wa ninu Loide iya-nla rẹ̀ ati ninu Eunike iya iya rẹ̀. A fi ipilẹ iwa rere ti Onigbagbọ lelẹ ninu ookan-aya rẹ̀ lati ọwọ iya rẹ̀ ati iya-nla rẹ̀.

Nigba ti a waasu Ihinrere Jesu Kristi ni Listra kiakia ni ọkan Timoteu gbá otitọ naa mú. A yi i pada di Onigbagbọ, o si di ọ̀kan ninu awọn oloootọ alufaa fun Paulu. Paulu pe e ni ọmọ oun ninu Ihinrere. Episteli meji ti Paulu kọ si Timoteu jẹ́ apa kan awọn iwe ti o wà ninu Bibeli, wọn si fun wa ni ẹkọ ti o niyelori nipa ododo. A ri apẹẹrẹ rere nipa ipá ti awọn obi ni lori ọmọ wọn ninu igbesi-ayé Timoteu.

### Itọni Rere Abrahamu ninu Ile

Oluwa sọ nipa Abrahamu pe, "Nitoriti mo mọ̀ ọ pe, on o fi aṣẹ fun awọn ọmọ rẹ̀ ati fun awọn ara ile rẹ̀ lẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o mã pa ọ̀na OLUWA mọ́ lati ṣe ododo ati idajọ" (Gẹnẹsisi 18:19). Nitori ti Abrahamu kawọ ile rẹ̀, Oluwa ka a si ẹni ti Oun le fi aṣiri ohun ti Oun fẹ ṣe hàn. Ọ̀wọ nla ni a bu fun Abrahamu ni ọna ti o gba n tọ awọn ọmọ rẹ̀.

A sọ fun ni ninu Majẹmu Titun pe ẹnikẹni ti o ba n fẹ oyè alagba tabi ti bişọpu ni lati jẹ ẹni ti o kawọ ile ara rẹ̀ girigiri, "ti o mu awọn ọmọ rẹ̀ tẹriba pẹlu iwa agba gbogbo" (1 Timoteu 3:1-4).

### Jobu

Jobu jẹ́ ẹni ti Oluwa sọ nipa rẹ̀ pe o jẹ oloootọ ati ẹni ti o duro ṣinṣin, ẹni ti o bẹru Ọlọrun ti o si korira iwa buburu. Nigba gbogbo ni o n rú ẹbọ sisun fun awọn ọmọ rẹ̀ pe boya ninu ase wọn, ọkàn wọn yoo yipada kuro ninu ododo si ifẹkufẹ ayé ati ẹ̀ṣẹ. O jẹ oloootọ si awọn ọmọ rẹ̀ ṣugbọn ko sọ wọn di oriṣa ki o si maa bọ wọ́n. Nigba ti a gba wọn lo kuro lọwọ rẹ̀ lojiji ati lai ro tẹlẹ, oun ko bu Ọlọrun, bẹẹ ni ko pe Ọlọrun lẹjo pe ki ni ṣe ti iru nnkan bẹẹ ṣẹlẹ si oun. O tẹ ori ara rẹ̀ ba o sin Ọlọrun o si wi pe, "OLUWA fifun ni, OLUWA si gbà lọ, ibukun li orukọ OLUWA."

### AWỌN ỌMỌ ALAIGBỌRAN

Ni nnkan bi ogoji ọdun sẹyin ẹni kan ti ko gbagbọ pe Ọlọrun wà mu ẹkọ ma-ba-ọmọ-wi tọ awọn eniyan ilu Amẹrika lọ. Jẹ ki o dagba funra rẹ̀ lai si ibawi ati lai si itọni, eyi yoo mu ki o le da ronu, yoo si le dá huwa gẹgẹ bi ẹda. Nipa bayii orilẹ-ede Amẹrika yoo kun fun awọn eniyan alagbara ati aṣayan eniyan. Ṣaaju akoko yii awọn olukọ ilu Amẹrika ti bẹrẹ si i tẹ̀ si ilana igbalode ninu iṣe wọn, nitori naa kia ni wọn tẹwọ gba ẹkọ́ yii ninu awọn ile-ẹkọ. Awọn obi fara mọ ọn, awọn ọmọde si fi tayọtayọ gba a. Nisisiyii wọn n jẹ ere ẹkọ naa. Iru ikore wo ni o mu wa? -- Awọn ọmọ alaigbọran ti o pọ pupọ to bẹẹ ti ọwọ ọlọpa ilu ko ka wọn mọ ni. Ki ni ere ti awọn obi ri gbà? Ipaya, ibanujẹ, arodun ati ainireti ti o ṣoro lati fara dà. Ikore wo ni ayé n ká? Ailofin, ija, iṣọta, ikorira, ainigbẹkẹle ati ibẹru.

Ki i ṣe ilu Amẹrika nikan ni nnkan naa pẹkun si, ṣugbọn o kari gbogbo ayé. Ro irú obi ti awọn ọmọ alailofin wọnyii yoo dà, iwọ yoo si ni òye iru eniyan ti ọpọ awọn obi ode-oni jẹ́. Ani laaarin awọn ẹlẹsin ti wọn n fi ẹnu jẹwọ pe awọn gbọran si Ọrọ Ọlọrun, wọn n gba awọn ọmọde laye lati yan ọna ti ara wọn, gbolohun ti o si n jade lode oni ni pe "Ẹyin obi, ẹ maa gbọ́ ti awọn ọmọ yin." Bibeli kọ ni pe, "Ẹnyin ọmọ, ẹ mã gbọ ti awọn obi nyin li ohun gbogbo: nitori eyi dara gidigidi ninu Oluwa" (Kolose 3:20).

Ọlọrun boju wolẹ lati ibẹrẹ akoko O si ri awọn nnkan wọnni ti yoo maa ṣẹlẹ ni igba ikẹyin ọjọ, O si kọ ọ silẹ ninu Ọ̀rọ Rẹ̀ pe: "Ni ikẹhin ọjọ igba ewu yio de. Nitori awọn enia yio jẹ olufẹ ti ara wọn, olufẹ owo, afunnu, agberaga, asọ̀rọbuburu, aṣaigbọran si obi, alailọpẹ, alaimọ́," (2 Timoteu 3:1, 2).

**Ibawi**

Igba miiran wà ti ọmọde yẹ fun ibawi, awọn obi gbọdọ ni ọgbọn pupọ lati mọ bi o ti tọ́ ati bi o ti yẹ ati akoko ti wọn ni lati ṣe ibawi yii. Paulu wi bayii pe, "Ẹnyin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ nyin binu, ki wọn má ba rẹwẹsi" (Kolose 3:21). Ninu Heberu 12:9 a ka bayii pe: "Pẹlupẹlu awa ni baba wa nipa ti ara ti o ntọ́ wa, awa si mbu ọlá fun wọn." Obi ko gbọdọ binu to bẹẹ ti yoo fi ikorira jẹ ọmọ rẹ̀ niya. Ibawi ti a n fi ikanju ati ailọgbọn ṣe ni o n mu ọmọde rẹwẹsi. Nigba ti a ba ti ṣe alaye fun ọmọde pe o ti ṣe ohun ti ko tọ́, o si ni lati jiya nitori ohun aitọ́ tabi nitori aigbọran rẹ̀, nigba naa ni ọmọde to le mọ dajudaju idi rẹ̀ ti a fi jẹ oun niya. Ni ọjọ iwaju, bi ko ba tilẹ jẹ lẹsẹkẹsẹ ọmọ naa yoo fi iyin fun awọn obi rẹ̀. Nigba pupọ obi maa n kẹdun nigba ti o ba n na ọmọ rẹ̀. "Gbogbo ibawi kò dabi ohun ayọ̀ nisisiyi, bikoṣe ibanujẹ; ṣugbọn nikẹhin a so eso alafia fun awọn ti a ti tọ́ nipa rẹ̀, ani eso ododo." Itọni ti awọn obi n ṣe fun awọn ọmọ wọn a maa fi hàn boya ọrun apaadi ni awọn ọmọ naa yoo lọ tabi Ọrun rere. Wo bi itọni ọmọde ti jẹ́ iṣẹ ribiribi to! Sibẹ ogunlọgọ ile ni o wà lode-oni ti kò ni pẹpẹ adura! Nibo ni iwọ ti ri awọn ọmọde ti a n kọ ni Ọ̀rọ Ọlọrun lowurọ, lọsan ati alẹ?

**Ohun ti Ofin Wi nipa Ọmọde**

Nigba ti a fi Ofin fun Mose, Oluwa mọ bi o ti ṣe danindanin to fun awọn obi lati kọ́ awọn ọmọ wọn nipa ti Ọlọrun, O si fi aṣẹ yii fun wọn: "Ki iwọ ki o si fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo agbara rẹ fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ. Ati ọrọ wọnyi, ti mo palaṣẹ fun ọ li oni, ki o mã wa li aiya rẹ: ki iwọ ki o si mã fi wọn kọ́ awọn ọmọ rẹ gidigidi, ki iwọ ki o si ma fi wọn ṣe ọ̀rọ isọ nigbati iwọ ba joko ninu ile rẹ, ati nigbati iwọ ba nrin li ọ̀na, ati nigbati iwọ ba dubulẹ, ati nigbati iwọ ba dide. Ki iwọ ki o si so wọn mọ ọwọ́ rẹ fun ami, ki nwọn ki o si ma ṣe ọja-igbaju niwaju rẹ. Ki iwọ ki o si kọ wọn sara opó ile rẹ, ati sara ilẹkun ọ̀na-ode rẹ" (Deuteronomi 6:5-9). Joṣua mọ awọn ẹ̀kọ yii yekeyeke ati ninu ọrọ idagbere rẹ̀ si Israẹli o wi bayii pe, "Bi o ṣe ti emi ati ile mi ni, OLUWA li awa o mã sin."

**Ifẹ ati Inu Rere**

Awọn obi ni lati jẹ orisun ọgbọn, ifẹyinti ati itọni fun awọn ọmọ wọn. A gbọdọ fi adùn ti o wà ninu ifẹ ati inu rere awọn obi hàn fun awọn ọmọde. Wọn yẹ fun ibawi ṣugbọn wọn tun yẹ fun iṣiri pẹlu. "Ọlọgbọn ọmọ ṣe inu-didun baba rẹ, ṣugbọn aṣiwere ọmọ ni ibanujẹ iya rẹ̀."

Ranti owe igba ni ti o wi pe, "Ọwọ́ ti o tọju ọmọ ni o n ṣe akoso ayé." Ẹnyin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ nyin binu: ṣugbọn ẹ mã tọ wọn ninu ẹkọ́ ati ikilọ Oluwa" (Efesu 6:4).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ipá ti iwọ rò pe igbesi-aye iwa-bi-Ọlọrun ni lori ọmọde?
2. Ki ni orukọ iya-nla Timoteu ati orukọ iya ti o bi i?
3. Ki ni aṣayan iwa rere ti iwọ ni?
4. Ki ni ṣe ti Oluwa fi ni irú igbẹkẹle ti O ni ninu Abrahamu?
5. Gẹgẹ bi Ofin, nigba wo ni awọn obi ni lati bẹrẹ si fi Ọ̀rọ Ọlọrun kọ́ awọn ọmọ wọn?
6. Irú iwa wo ni o gbilẹ lode-oni laaarin awọn ọmọde ẹni iwa-bi Ọlọrun; laaarin awọn ọmọde alaiwa-bi-Ọlọrun?
7. Ka ọrọ idagbere Joṣua si Israẹli nipa sisin Oluwa.